**Owe**

Adię iba l'oko, iba l'atinan je nkan. Imado iba se bi ęiplę a ba'lu je, Eru iba l'oba, enia ko ba ti'ku'okan.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia ma jeki l'enia suawon, l'eni ma son-wọn ko ni gb'e, Apa ọmọde ko le ka iti Oso, yio ma doyika.

VOL. XII No 697. LAGOS. SATURDAY OCTOBER 15, — OCTOBER 21. 1960. KỌBỌ MEJI (2D)


# GONGO SO NILE CONGO,
## ILE NIGERIA FI OMO OGUN RANSE

Lọjọ Alamisi (Thurday) ọjọ kẹtala oṣu yi ni Ijọba ilẹ Nigeria fi awọn Ọgagun mejila r a n ṣ ẹ silẹ Congo lati lọ foju finlẹ de awọn ọmọ ogun ti yio lọ ṣe iranlọwọ lati pa'na rogbodiyan awọn onijọngbọn ti o nda ruke-rudo silẹ nilu na.

A gbọ wipe laipẹ yi ni ọwọ awọn ọmọ ogun ti yio lọ na yio dide ni Nigeria. Awọn Ọga'gun ti nwọn ran lọ na ni Major General N.L. Foster ati Lt.-Col. Aguyi Ironsi pẹlu awọn enia mẹwa miran.

ỌRỌ ILẸ CONGO D'OJU OGOGORO

Irohin ti o ṣiwaju niti Ọga'gun Joseph Mobutu ti o fi awọn Ṣọja yi ile Ọgbẹni Patrice Lumumba ka, wipe bi o ba jade pẹrẹ ki nwọn o ki mọlẹ gbe lọ ju si itimọle. O tilẹ ti kọwe ranṣẹ si Akọwe ẹgbẹ Majẹoba Agbaiye nipa rẹ.

## Nigeria Wo Egbe Majeobaje Agbaiye

NEWYORK— Ni ọjọ Jimọ ( Friday ) ọsẹ tokọja ni ẹgbẹ Majẹobajẹ Agbaiye fi tayọ-tayọ gba Nigeria sinu awujọ ẹgbẹ na. Nigbati nwọn fi iwe ifiwọ ẹgbẹ ti Nigeria kọ siwaju ẹgbẹ ni dede agogo mẹrin, nwọn gba t'ọwọ-t'ẹsẹ sinu agbo rere wọn na.



Ọjọ nla ni ọjọ na je fun gbogbo ọmọ Nigeria. Olotu ijọba Apapọ na Alhaji. Sir. Abubakar Tafawa Balewa ti yọ bi oṣu larin awọn olubẹwo agbaiye ni ọjọ na nigbati o dide sọrọ ninu awujọ wọn; o dupẹ lọwọ igbimọ fun gbigba ti gbogbo awujọ ẹgbẹ na fi inu didun gba Nigeria tọwọ-tẹsẹ sinu igbimọ agbaiye na.

Nigbati Olotu ijọba pada de lati New York, ninu awujọ igbimọ agbaiye, o ba

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Omoba Alexandra Nile Oke-Oya

Ọmọba Alexandra ti de ilẹ Oke-ọya lati ọjọ Tuesday ọsẹ yi. Lati igbati ọkọ ofurufu ti o wọ ti gunlẹ ni Alhaji Sir Ahmadu Bello, Sardauna Ṣokoto ti iṣe Olotu ijọba Ariwa ti tẹwọgba alejo.



Lowurọ ọjọ Alamisi ni awọn enia Ariwa ṣe

( Wo yoku loju ewe kẹjọ.)

# ELECTRICITY CORPORATION OF NIGERIA

## INVITATION TO TENDER

### BUSH CLEARING

Tenders are invited from responsible Contractors for the following Contracts:-

(1) Maintenance of Transmission Line Trace: Shagamu--Ibadan 132kV Transmission Line.

(2) Bush Clearing: Ibadan--Erinle (Ede) 132kV Transmission Line.

Tender documents comprising Tender Form, Form of Contract and Specification of the Contract etc. may be obtained from the Acting Secretary, Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarters, Private Mail Bag 2030, 13, Broad Street, Lagos, on payment of a deposit of £5 per Contract. The deposit will be refunded on receipt of a bona fide Tender. Tenders received in any other manner will not be considered.

It is essential that tendering Contractors shall be in a position to produce evidence of having successfully undertaken previous Contracts of a similar nature. The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any Tender.

Further information concerning this Contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

**George W. Nicol**
ACTING SECRETARY TO THE CORPORATION


# OBA OBINRIN NDABIRA LORI ESIN



Alaiyeluwa, Oba Obinrin, Elizabeth Keji, gegebi aṣa ti nwọn ma nfi ere ọmọ-Ogun ṣe ariya ọjọ ibi rẹ ninu oṣu June, l'ọdọdun, ti awọn ọmọ ogun yio gun ẹṣin niSa nwo ti Alaiyeluwa Ọba'binrin na ngun ẹṣin lọ sibi ariya ọjọ ibi rẹ yi.

# AWON IIETO TO WA L'OKUN ALASIA D'ERU JEJE

EKO - Gẹgbi irohin ti o ta siwa leti lati ọdọ awọn Ọlọpa, gbogbo Iieto, awọn ilu kekeke ti o wa lọna Okun Alasia ti di ẹru jẹjẹ nisisiyi fun awọn ologbe ibẹ.

Iyọnu awọn "firi tidi Olẹ, olọ k'onihun kigbe" ti papọju, gbogbo ohun ini awọn enia ni awọn Ole ti ko lọ.

A bẹ awọn ọlọpa ki nwọn jọwọ gba awọn enia na silẹ Ọna l'o ngba alailara.

# Omo To Lo Keko Nilu Oyinbo W'ewon

ABEOKUTA. Ọmọ Akẹkọ kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni C O. Adeyọsoye bi ọmọ ọdun mẹdọgbọn, ti o lọ kọ iṣẹ Agb'ẹjọro (Lawyer) nilu Oyinbo ni awọn ọlọpa lọ mu pada wa fun ẹsun afijibiti gb'owo.

Nwọn sọ wipe Adeyọsoye fi eru gba adọrun pọnun (£90) lọwọ Omidan Akintọla ti nwọn jijọ nṣiṣẹ (Wo yoku loju ewe kejo)


## ARADAN NARVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun Imarale agba ati aremo pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun imarun ẹjẹ dudu, isokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun ailokun nkan ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ ku bi ojo" 3/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6 e.g. 7/- Post Free

THE EGBA TRADING ARADAN STORES
112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2. Ebute-Metta.

Phone: 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.






# Olori Alufa Si Sosi Titun Ni Ibadan

**IBADAN.** Olori Alufa tilu Oyinbo Dr. Geoffrey Fisher, şi ile isin, Ş şi Arẹmo titun ti nwọn şẹşẹ kọ silu Ibadan loju ogunlogọ awọn enia pataki pataki. Şọşi na yio gba bi irinwo-le- lẹgbẹrun enia awọn olusin Kristiani.

Ọpọlọpọ awọn enia ni ko bikita fun ojo ọjọ na ti nwọn peju-pesẹ, paapa nitori ati le f'oju ganni Olori Alufa Dr. Fisher ti o wa şi ile isin na.

Lẹhin iwasu rẹ ni o si aworan iranti kan loju Aşiwaju ijọ Alatako nile igbimọ Apapọşe, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati iyawo rẹ, Olubadan ilu Ibadan, Ọba I. B Akinyẹle, Alufa Ondo ati agbegbe rẹ, S. O Odutọla ati awọn Olori Alufa to ti gba isinmi meji, Bişọpu S. O. Phillip ati A. B. Akinyẹle ati awọn ọpọ enia.

Awọn ti o fi ọla wọn bukun şişi ile isin na ni Alabojuto işẹ irohin ijọba, Oloye Fadayiro ati iyawo rẹ, Oloye G. Akin Dẹkọ ati iyawo rẹ, Dr. F. O. Omitowoju ati iyawo rẹ, Ọwa Ilesha, Ọba Biladu 111, Bişọpu Ijọ enia dudu ni Ibadan, Ẹni - Owọ Abọyade Cole ati awọn enia jankan - jankan ninu ẹlẹsin igbagbọ ni ọsẹ wọn pe sibẹ.

# Sultan Ilu Zanzibar D'ologbe

KẸNYA - Gbukẹ Ya gbọ wipe Sultan (Ọba) ilu Zanziba ilẹ Kenya, ti o ti le ni ọmọ ogorin ọdun salaisi, nwọn si sinku rẹ ni agogo mẹrin irọlẹ ọjọ keji.

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O- NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ŞE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIŞOWO LE ŞE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IŞU AKARA GBIGBONA.

E Polowo Oja Yin
Sinnu Iwe Irohin
ELETI-OFE

# OWO L'OBINRIN MO

Nigba laılai, awọn ọrẹ meji kan wa nilu Arikọgbọn, nwọn jẹ kori-kosun arawọn. Bi ọrẹ wọn ti dun to, ọjọ kanna ni nwọn gbeyawo, aşọ kanna ni awọn mẹjeji ma nlo, ọrẹ wọn pọ to bẹ gẹ ti ẹnikan fẹrẹ ma mọ wipe nwọn ko nşe ọmọ iya kanna.

Ni ọjọ kan nigbati nwọn jẹ ti nwọn si mu amuyo tan, nwọn bẹrẹ si ta'kurọ sọ, orukọ ẹnikini njẹ Adejumọ, ẹnikeji njẹ Ọlaifa, Adejumọ sọ fun ọrẹ rẹ wipe "Owo ni Obinrin mọ" Ọlaifa ni, boya iyẹn le jẹbẹ, şugbọn ki işe bi ti iyawo ti on Adejumọ tun tẹnumọ fun ọrẹ rẹ pe gẹgẹbi adiẹ ti ko jẹ f'oju ri agbado kio ma jẹ ni obinrin ri pẹlu owo bi ọkunrin ba tile ri owo ko sinu apo şokoto rẹ, iba jẹ asuke tabi ayarọ enia, obinrin ko ni moju kuro lara rẹ

Ọrẹ keji ti o njẹ Ọlaifa yi taku wọnle wipe iru obinrin ti on ş'ọwọn, ko si owo ti ọkunrin le fi fa oju rẹ mọra. Bi eyi ko ba da ọ loju, jẹ ki a kọ'le le lori. Awọn mejeji si kọle pọnun meji-meji Nwọn fi adehun si ẹhin oşu mẹta wipe ti Adejumọ ko ba ri ọna ba wọ, yio san pọnun meji fun ọrẹ rẹ, Ọlaifa.

Nigbati o di oşu keji ni Adejumọ to ri aye, ni asiko ti Ọlaifa lọ si idalẹ bi ọjọ mẹta kan, ki o to de, nigbati Adejumọ ba nlọ ki iyawo ọrẹ rẹ ku ilode ọkọ rẹ, yio lọ wa owo şile bi ogoji tabi ọgọta ko sinu apo şokoto rẹ, bi o ba ti de ọdọ iyawo ni yio towọ bọ apo, yio si ma mi i, nibiti o gbe nki iyawo ku idele ọkọ rẹ, yio si ma bu owo na jade bi ẹnipe o fẹ ka tabi o fẹ fi fun iyawo na. Şugbọn ko ni şe bẹ, yio tun ko da sinu apo pada ni.

(Wo yoku loju ewe Kẹfa)

# ELETI - OFE

ANJUWON KO SE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI — OFE, LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23339

VOL. XII. NO. 697. SATURDAY OCT. 15, — OCT. 21, 1960.


## OMINIRA TI WOLE, KILO TUN KU?

Awọn Yoruba mọni-mọni, ni o ma nwipe "Owe ni ẹṣin ọrọ, bi ọrọ ba sọnu, owe ni a fi nwa" nitorina, idahun wa si ibere ti o jade lọnu wa ti a fi ṣe akọle wosika wa ọsẹ yi fun enyin onkawe wa, yio bẹrẹ pẹlu owe. "Eyiti o ku lẹhin ọlọ oju oje lọ", eyini ni pe ohun ti o ku lẹhin Ominira ki iṣe kekere.

Lọna kini, awọn aṣiwaju ẹgbẹ wa ti wọn fi ọpọlọpọ wahala ati ọgbọn inu pẹlu laakaye mu ominira wọlẹ Nigeria fun wa nilati fi arawọn ṣe ọkan, ki nwọn fi isowọpọ ṣiṣẹ ailabawọn gẹgẹbi eyiti wọn ti nṣe lati ẹhin wa, ti a fi gba ominira wa laisi it'ẹjẹ silẹ, eyiti o mu ki gbogbo awọn ilu okere, awọn ilu alagbara ma sala wa nilẹ Nigeria wipe a fi ni awọn enia ti nwọn peye ninu eto iṣelu lati mu ọpọ ijọba wa dani.

Lọna keji, ẹwẹ, awa paapa gẹgẹbi ọmọ ilẹ Nigeria, nilati mura giri, ki a fi gbogbo agbara wa ṣiṣẹ ilu wa, laiṣe imẹlẹ, ki a le gbe ogo ilu wa yọ, de'po ti awọn enia ilu okere ko fi ni le pada wa ṣuti enu siwa, ki a fi arawa han gẹgẹbi ọmọ ti wọn bi, ti o tun ara rẹ bi, eyiti Yoruba npe ni Ọmọluwabi.

Iṣẹ pọ lẹhin ominira, o d'ọwọ gbogbo wa.

## Oko Reluwe Pa Omode'kunrin Kan

EKO — Lọjọ Satide ti o kọja ni ọmọde ọkunrin kan bi ọmọ ọdun mejila ṣe agbako iku rẹ loju irin ọkọ Reluwe nitosi idikọ Mushin.

A gbọ pe nwọn ran ọmọ na niṣẹ lọ ra onjẹ ni ọsan ọjọ buru eṣu gb'omi-mu na ni ọmọde ọkunrin ti oruko rẹ njẹ Adebeyọ lọ rekọja lori irin ti o si ṣe konge pelu ọkọ ẹru Reluwe ti o pa ni apafọn.

Ki Ọlọrun ma jẹki a rin l'ọjọ r'ebi npọna.

## Olopa Onifere Nkose Fere Alabapo



Aworan Saji Ọlọpa ti o njẹ James Ojege ni a wo yi nigbati o nkọṣẹ Afunfere Alabapo nilu Oyinbo.

O fi fere rẹ na dara ni gba ariya Ominira Nigeria nilu Eko.

## Enia Ko Gbodo Ro Arare Pin

IBADAN Ọkunrin kan ti oruko rẹ njẹ Salawu Aremu bi ọmọ ologoji ọdun lori ni awọn ọlọpa ramu wa si Kotu niwaju adajọ fun ẹsun wipe o nfẹ pa ara rẹ.

Nigbati adajọ bi lere wipe ese ti o fi fẹ pa ara rẹ? Salawu sọ wipe on ro igbesi aiye on pin ni, nigbati on fa lọtun ko bọsi, on fa losi, ko bọsi, iwaju ko ṣe lọ bẹni ẹhin ko ṣe pada si, ni on ba kuku fi ero ṣ'ọkan wipe, on yio fi ọbẹ la ara on ni 'agbẹdu. Bi on ba ti le ku, ọrọ buṣe.

Adajọ ni iwọ ko mọ wipe enia ko gbọdọ ro ara rẹ pin, ko si ayipada ti Ọlọrun ko le ṣe fun ẹda ọwọ Rẹ. Nitorina ki o san pọnun marun-din-logoji si kotu tabi ki o lọ gb'ẹwa oṣu mẹrin.




# Owo Te Ajomogbe

EKO. Okunrin kan ti oruko re nje Aderanti Fashina ti o ngbe No. 4B, Amuto Street, nilu Eko, ni a gbo wipe o lo ji omode obinrin omo odun mejo kan gbe ni oja jankara ni ojo Jimo ti o koja.

Nigbati owo olopa te, nwon ba yeri golu meji lowo re, nwon si fura si pe boya ona jibiti ni eyi na gba de owo re. Awon olopa nse iwadi siwaju lowo.

# Enia Merin Ku Senu Ise

EKO - Agbejugbanu irohin ti a gbo niti awon enia merin ti nwon je onise gbena - gbena (Carpenters) nibi ise won. Awon enia ti o d'ologbe wonyi je onise abe awon Oyinbo Alagbase ise (Contractors) G. Cappa Ltd. ti nwon nko ile Ominira. (Indenpendence House).

A gbo pe isu koto ile ti nwon lo pade agbako iku ojiji yi jin sisale niwon ese medogbon, ati pe oorun buruku ti o ti gbojikan ninu koto na ni o se oniko iku won. Awon Oyinbo won meji ti nwon gbiyanju lati fa won jade tun fere f'ara gbalamo nitoripe, nwon nilati fa awon na jade kuro ninu koto ni, okan ninu awon mejeji si mbe nile iwosan ( General Hospital ) lesekan aiye esekan orun.

Awon Ologbe na nje Yekini Akano, Nicholas Igbokwe, Akande Muraino ati Ibitayo Ogundeko, Nwon ti ko awon oku na lo fun ayewo nile ayewo oku. (Mortuary).

Lowo iku ojiji Oluwa tere gbawa

# Ika Si Eranko Ko Dara

EKO - Ogbeni kan ti oruko re nje O. Bakare ni awon egbe "Ika si Eranko ko dara" ramu ni ona Iddo, nigbati o fi okun di ewure kan lese ti o gbe sinu apo to fi ko Basiku re lorun owo.

Nigbati ewure na ti nja, o ti nho ito futu lenu ki nwon to ri, nwon si mu lo si Kotu adajo bu sile mewa fun ni sisan (10/-) tabi ewon ojomerinla ti koba ri owo san.

## Adota-Le-rugba Enia F'ara Gba Bulala

GBOKO - Ninu rogbodiyan ti o be sile ni agbegbe ilu Tiv ati Bauchi ni owo awon olopa ti te enia bi ad,ta - le - rugba ti nwon fi sun esun bi atena-bole, o ni jamba nipa kiko awon ohun ija dani ma yi ilu ka.

Opolopo ninu nwon ni adajo Ogbeni A.H.R. Thomas sa konko bulala mefa - mefa fun u, o si ju awon enia bi metadin-logbon s'ewon osu kokan tabi ki nwon san owo ponun mewa mewa, iwonyi je awon ti o le l'omo ogoji odun awon enia merin - din - logun ti nwon fi sun esun atenabole ni adajo ju sewon osu mesan-mesan.

Awon odaran ti ko to omo ogun odun ni da sile pelu ikilo ayafi okan ninu won ti olopa fi sun esun adanasunle ni adajo bu bulala mesan fun u.

Odaran kan bi omo odun mokandinlogbon ni o daku ninu kotu, won si gbe lo sile iwosan nilu Mkn. Esun ti okunrin afoju kan ni nwon yo kuro nigbati awon olopa so wipe awon si mu ni. Ki adajo to se idajo le won lori, o so wipe ese ti awon enia na se buru papo ti o je asiko ti ominira ile Nigeria sunmo tosi yi ni irufe iwa janduku bawonyi njade.

## Alufa Nelson-Cole Yio Rin-Irin-Ajo

Eko. Alufa A. O. Nelson-Cole ti ijo awon enia dudu (U.N.A. Mission) yio rin irin ajo lo silu mimo Jerusalem ati ilu mimo Rome ni ojo ose ti o mbo, yio si gbiyanju lati ri Olori Alufa ijo Aguda lohun, Pope XXIII. Oko ofurufu ni Alufa Nelson-Cole yio ba fo lo lati ilu Eko.

## ILE GHANA PA NIGERIA L'ayo

Ninu ere bolu afesegba ti gbogbo Iwo-orun enia dudu, eyiti Ghana ati Nigeria gba pari ni ojo Sunday ojo kejo osu October 1960. ni gbangba odan (National Stadium) ni Suru-Lere, ni akoko ti Ghana pa Nigeria layo l'ori ile re ninu ere na. Won no Nigeria ni meta, Nigeria kosi mu okansoso.

Bi ere na ti lo ni wipe, Dr. Kwame Nkrumah ti ise Baba egbe ile Ghana ni o fi ife oni golu ta awon elere bolu afesegba ti gbogbo Iwo - orun ile enia dudu lore, ti won si ja jakadi le lori Nigeria sagbara ki o le te on lowo, bakanna ni Ghana ko sunmi rara.

Nigbati ojo pe ti won nlati ponde ni gbangba odan (National Stadium) ni Suru-lere, gongo so opo enia jankan-jankan l'o wa lati ile Ghana wa wo ere na. Ese awon asoju oselu ile Nigeria paapa pe sibe simusimu.

Nigbati ese pe tan, ti awon elere na si bere si se bi alarakumapa'la, otun nja ki on le bori, osi na si nsa gbogbo agbara re.

Koiti ju iwon iseju meta ti won bere ere na lo ti okan ninu awon osere Ghana ti won npe ni Acquah ti fi ogbogbon ati ereto gba okan wole Nigeria. Nigbati o to iwon igbati ere na nlo si iduro fun isinmi igba die, ni awon omo Ghana tun raye gba ekeji ati eketa wole pelu asise omo Nigeria kan laimo pe yio lo be.

Awon Orilewode ti o lowo sinu ere na jre merinla (14). O tun di odun ti o mbo ki a to tun se iru ere bayi.

Ki Oluwa so wa di opolopo odun. (amin)

## SULTAN ILU ZANZIBAR D'OLOGBE

(O bere loju ewe keta)

O g'ori oye oba nigbati Ali - Bin - Hamoud - Bin - Mohamed, fi ori ite sile ninu osu December, 1911. Ilu Zanzibar ti l'ori sabe Gesi lati odun 1890 lasiko Oba ighana. Eniti yio ropo re ni omo re okunrin Seyyid (Omoba) Sir Abdulla - Bin-Khalifa.

Oba ti o w'aja yi ti fi oju re ri igbade Oba meta nilu Oyinbo. O lo silu Oyinbo nigbati Ologbe Oba George, Karun gbade ni 1911, Oba George, Kefa ni odun 1937 ati nigbati Oba Obinrin Elizabeth, Keji, gbade ni odun 1953. O tun lo be ilu London wo ninu odun 1929.

Ki Oluwa gbe si afefe rere.

## Owo L'obinrin Mo

(O bere loju ewe keta)

Nigbati o ndi igbagbogbo ti o ma nse bayi, iyawo pe ni ojo kan, o wipe, enyin ti e je ore oko wa, e ko tile fi owo lo wa, nse ni e nka ti e tun nda sinu apo pada. Adejumo ni, beni, nko le fun o lowo ni, nitoripe ko si iye owo ti emi ko le fun obinrin, sugbon eyiti nko ba ni le ba lopo, emi ko je fun lowo. Iyawo ni iyen na ni nkan danindanin loju re ? nkan kekere ni, ko lenu depo ti yio rojo fun enikeni.

Adejumo si dahun wipe bi o ba je be, nko ni ko lati fun o, sugbon ki o gba sile marun yi ki o fi po eko mu l'owuro ola, bi mo ba de ihin ni irole ngo mu owo die dani wa fun o. Iyawo gba owo na, o so wipe ngo ma reti re lola o, masalai wa o.

Nigbati ojo nro lo ni ojo keji, iyawo ore ti wa nkan adidun sile fun Adejumo, ore oko re, lati fi pa'nu ti o ba de.

( Koiti pari )

## Ijoba Iwo - Orun Fi Ara Ghana Je Adajo Agba

IBADAN. Ogbeni Adajo S.O. Quashie - Idun ti ise ara ile Ghana ni Ijoba ipinle Iwo-orun ro si eto lati fi je oye Adajo - agba ni ipinle na, ati pe yio bere si lo ipo na lati ibere osu October 1960.

Iba itan die ti a gbo nipa adajo - agba na ni wipe ni ilu Cape Coast ni a ti bi i, o si je ilu nla kan labe ile Ghana, ni odun 1902. O bere eko re nile Ghana o si pari eko re ni Selwyn College nilu Cambridge, ibe lo gbe kose Ofin ati itan atowodowo. O gba oye amofin ninu odun 1927.

Latigba na wa lo ti nse ise amofin ni ile Ghana titi di odun 1936 ki nwon to gbe e si ipo adajo kotu kekere. Larin meji odun 1941 si odun 1948, nigba pupo lo se ise akowe agba kotu na nile Ghana, lehinna lo tun pada di adajo kotu Ganran.

Larin odun 1944 si 1945, o ba awon adajo meta sise ni Kotu Kotemilorun, o gbo iwo adajo Kotu nla ninu odun 1956 o si de'le de adajo agba nibe. Ninu odun 1957 ti o de silu Eko, o nse adajo ninu kotu nla nilu Eko fun igba die, ki o to di adajo ni Kotu nla ti Iwo-Orun Nigeria.

## Omo To Lo Keko Nilu Oyinbo W'ewon

( O bẹrẹ loju ewe keji )

ninu Ile Iwosan (Hospital) kanna pẹlu ẹtan pe on yio ba gbawe ọkọ ti awọn mejeji yio wo lọ silu Oyinbo. Nigbati ọwọ rẹ tẹ owo na, jagun ba ọkọ ofurufu fo lọ silu Oyinbo pẹlu iyawo rẹ.

Omidan Akintọla lọ fi ọrọ na han awọn ọlọpa ti nwọn fi siwaju adajọ ti o ṣe iwe ipa lati fi mu pada wa lati ilu Oyinbo. Adeyọsoye sẹ kanlẹ pe on gba owo na ni ọna eru, ṣugbọn o ni on gb'owo na on si ko fun Ọgbẹni Cole kan ki o ba gbawe ọkọ.

Adajọ Ọgbẹni C. A. Piper sọ ninu idajọ rẹ pe ika enia alailanu ati ogbogi opurọ ni ọdaran yi, iwa aiṣododo lori iṣẹ mi ati alebu nla ni yio jẹ fun ilẹ Nigeria bi mo ba ṣanu iru enia bayi, nitoripe iwọ ko yẹ fun iṣẹ ọla rara de'po ti o kọṣẹ ag'ẹjọro.

Nitorina, ki o lọ gb'ẹwa oṣu mẹsan.

## Awon Soja To Lo Sere Nilu Oyinbo



Awọn Ṣoja mejeji ti a'nwo ninu aworan yi, Saji Mejọ, Nathan Dilli ti ijọ ọmọ-Ogun Keji, ati Saji Mejọ, Amadu Katsina, B. E. M. R. S. M. ti ijọ ọmọ Ogun Kẹta nilẹ Nigeria pẹlu Saji George Higgins, ọmọ Ogun tilu Oyinbo ni Bareke Woolwich, ni London, ni nwọn jijọ nẹwọ yi.

## Igbesi Aiye Jesu

(Lati Ọwọ. John Awojulagbe)

Gbogbo onigbagbọ agbaiye ni akojọpọ, ti nka a ninu iwe mimọ, o si ti ngbọ ninu iwasu awọn ẹniti o ni Mimọ, pipọ ninu ọrọ Ọlọrun nipa iṣẹ nla ti Jesu Oluwa ti ṣe ni ode aiye kanna yi. Nitoripe lati igbati Jesu ti goke rẹ ọrun, aiye yi ko ti parun ri, iyatọ ti o wa nibẹ ni ilaju ti a nri lati igba de igba.

Ṣugbọn sibẹsibẹ aiye kanna ni a si ngbe di oni yi. Njẹ nipa eyi, igbesi aiye Jesu Krisiti dabi igbati Baba kan ba nsọ itan igbesi aiye Baba rẹ fun ọmọ rẹ. Bayi ni ao si ma sọ igbagbọ ti a ni ninu Jesu Kirisiti, ati igbesi aiye rẹ lati iranderan titi lailai.

Kirisiti la oju afọju, o ji oku dide, o mu ki aditi gbọran o mu adẹtẹ larada, o le ẹmi Eṣu kuro lara ọmọ enia, o fi onjẹ enia kanṣoṣo bọ ẹgbẹrun enia.

Ṣugbọn sibẹ-sibẹ, awọn ọta rẹ nfi ye wa pe agbara ẹmi Eṣu ni o nlo lati ṣe iṣẹ iyanu gbogbo ti o ṣe.

Lọjọ oni, awa tun ri nkan ajeji, ninu ọgbọn iwe lati fi dabaru awọn ohun iyanu wọnyi. Awọn miran ẹwẹ, ngbinyanju pẹlu gbogbo agbara wọn tabi ninu ọgbọn tabi ninu aimọ, pe ki wọn le sọ awọn ohun iyanu wọnyi di irọ fun awọn ti o ni igbagbọ ninu rẹ.

Ṣugbọn gbogbo iṣẹ iyanu ti Jesu, ti Jesu ṣe ni awọn ti o pa poara ti yẹwo, ti nwọn si ri pe otitọ ni. Tabi ari enitii o le sọ fun wa pe awọn afọju ti o la oju wọn yẹn ko tun riran mọ, tabi ti o le sọ fun wa pe awọn aditi ti o gbọran ko tun gbọ mọ nigbẹhin, tabi ti o le sọ pe Lasaru ko ku, ṣugbọn nṣe ni nwọn di bi oku fun ọjọ mẹrin, tabi pe Jesu paapa ko ku rara, ki a to sọ pe oji nde ?.

Iṣẹ iyanu Jesu ti jẹri si gbangba pe, nṣe ni Ọlọrun ran wa si aiye, eleyi si tun nfi kun ọrọ rẹ, paapa o tun fi anu rẹ han ni lori ọmọ enia, o fi agbara igbala rẹ han ati gẹgẹbi ati ṣe ni lati ni oju anu si ẹnikẹni.

Ọsẹ to mbọ, ao tun kọ nipa iṣẹ iyanu Atunbi.

## Egbe Odozi-Obodo Wolu Tiv.

GBOKO - Awọn ọlọpa ni ifura wipe awọn ẹgbẹ buburu kan ti nwọn npe ni Odozi - Obodo nilu Abakaliki nilẹ Ila-orun, eyiti nwọn yẹgi fun akonijẹ wọn lasiko kan laipẹ yi lori iwa buruku wọn, ti wolu Tiv wa pẹlu awọn janduku enia to nfọle ji ẹru ọlẹru ko lọ.

Awọn Ọlọpa leru wipe awọn enia na riti rogbodiyan ti o nṣẹlẹ ni asiko yi fi kẹwọ lati ma fi ṣe iṣẹ j'amba wọn.

Awọn ọgọgorun enia ti nwọn ti sọ di alainile lori, ni nwọn ti sa asala silu Gboko. Awọn ẹgbẹ Alagbelebu Pupa (Red Cross Society). l'o nṣe itọju wọn.

## Nwon Ju Oko S'ewon Iyawo Bu S'ekun

EKO - Ni kotu Yaba ni ọjọ Alaruba (Wednesday) ni ọmọbinrin a d e l e b ọ kan b u s'ekun gbaragada nigbati nigbati a d a-jọ j u ọ k ọ r ẹ Beniah Chikwendu, s'ẹwọn odun meji ati oṣu mẹta fun ẹsun ole ti nwọn fi sun wipe o ji owo bi pọnun mẹrin - le - ladọsan, ṣ i l e mejila abọ, lọwọ ọga rẹ.

Awọn ọlọpa s ọ f u n adajọ wipe n i n u o ṣ u June, ọdun to kọja n i aṣiri t u pe Chikwendu ti gba owo na ti ko si fi jiṣẹ. Nigbati ọ g a i l e iṣe ṣe abere ẹhin wo lọwọ r ẹ, o jẹwọ p e otitọ n i on gba owo na, o n s i t i na, o si jẹleri p e o n y i o san pada. Lẹhinna n i nwọn mu wa si Ṣobu ọlọpa.

Lọya rẹ sọ wipe Chikwendu ko owo na fun Onipibi to fẹ sọ di ilọpo meji ni eleyini gbe salọ.

Adajọ O g b ẹ n i J. A. Adefarasin sọ wipe o jẹ iyalẹnu pe irufẹ eleyi kowo lọ f u n Onipibi aṣowo d i ilọpo meji ti o w o ọ g a rẹ k o t o. Irufẹ ibiti [illegible] t i n ṣ e nilu yi ti pẹ ti ko si ṣiṣiti owo tirẹ di ilọpo meji ri. Nitorina, ọdaran yi nilati j i y a ẹṣẹ na.

## Nwon Gun Asiwaju Ijo Alatako L'obe Pa

TOKYO - "Kosi i b i t i ẹṣẹ kosi, ti ile wọn l'opeleke" ni a l e s ọ s i ọrọ t i i l u Japan yi. Ọgbẹni Inejiro Asanuma, Olori Alatako igbimọ ilu na ni a gbọ wipe ọmọ ọdun mẹtadilogun, Otoya Yamaguchi g u n l ọ b ẹ pa larin ilu na.

A gbọ wipe awọn enia bi ẹgbafa ni nwọn t' o ti nwọn nlọ si ile Igbimọ pẹlu ijọ ajọ lọ wele ati asia popa lọwọ olukuluku wọn, ti nwọn si nkọrin pe ki ijọba Ikeda fọ.

Ọbẹ ti o fi gun Olori Alatako na pa g u n to Iuṣi mọkanla, nibiti iyẹn gbe mba ọpọ awọn enia s rọ ilu. Pẹlu ẹjẹ ṣoroṣoro ni nwọn g b e d e Ile I w o s a n. (Hospital). Ṣugbọn o d'oku ọ r u n nibiti nwọn ti nṣiṣẹ fun lẹsẹkẹsẹ.

## Nigeria Wo Egbe Majeobaje

(O bere lo j u ewe kini)

awọn Oniwe irohin sọrọ, o si wipe ọrọ ti on sọ nipa ti Kongo ni nwọn gba. Ati pe ilu New York fi han on pe ẹru nla mbẹ fun wa lati ru

Awọn ti o ba Olotu wa lọ si i p a d e Majẹobaje Agbaiye na ṣi wa lọhun lati ma ba wọn ṣe ipade. Alhaji A b d u l Maliki, Aṣoju agba ilẹ Nigeria nilu Oyinbo ba Olotu ijọba wa de, ṣugbọn nwọn ko sọ ohun ti o wa ṣe.

## Ojo Nla Ro Wole Nilu Eko

EKO Ojo nla kan rọ ni ọjọ Iokanla oṣu yi t i i ṣ e ọjọ Alaruba, (Tuesday), ojo na pọ da'po to fi w o -ile, Opo ile ni o wo ni okun Alasia ati Ijẹ mu Eko.

Awọn Opopo ọna nla meji ni omi kun dẹdẹ ti ko ṣe gba kọja, awọn Opopo ọna na ni Oko Awo ati Olowogbowo.

## Orogun Ile Ila D'ologbe

IBADAN - Oba Agboluaje Keji, Ọrangun Ile - I l a ni a gbọ wipe o w'aja ninu afin rẹ n i owurọ ọjọ Atalata, (Tuesday) ọsẹ yi.

Ọba yi ku f'aiye s i l ẹ nigbati o dagba d i ẹni ọgọta ọdun l'aiye.

Ọrun rere o.

### ỌMỌBA ALEXANDRA NILE OKE - ỌYA

(O bere lojo ewe kini)

konigbagbe ere ẹṣin fun ọmọba na nilu Ṣokoto, o le lẹgbẹdogun ẹṣin ti o ṣere ariya na fi k i ọmọba Alexandra ku abọ.

Gbogbo asiko ti nwọn fi ṣe mopa-bambari ere yi ko ju wakati meji lọ, Ọmọba Alexandra paapa fihan p e o n g b a d u n e r e n a, o s i s ọ w i p e o n ki yio gbagbe ohun ti oju on r i nilẹ Ariwa lailai.

L'ọsan Oni ni Ọmọba Alexandra yio f i ilẹ Nigeria s i l ẹ lati Kano lọ si ilu rẹ.

Adele bare o.

## Omo To Ba Gboran Yio Je Amala Lodo Agba.

Ọmọde k a n m b ẹ n i Igando, orukọ rẹ njẹ Aṣereke, o jẹ ọmọ ti o le, o si n i aja kekere k a n, o jẹ ọmọ ti o fẹran lati ma ba gbohun-gbohun ṣ e r e nitori eyi, a ma ṣere lọ sinu igbo ki o ba le ri aye lati ma ba gbohun-gbohun ṣere.

Lọjọ kan ti o ṣere lọ sinu igbo, bẹni o ri ile kekere kan, larin igbo, ọgba s i yi ile na ka. Aṣereke j ẹ ọmọ ti o mọ iwe Yoruba ni kika diẹ, nitoripe, o nlọ sile ẹkọ. O ri orukọ kan ti nwọn kọ si ara ilẹkun ile na wipe, wọ ile wa.

Aṣereke pe aja rẹ mọra, nwọn si wọle. Bi nwọn ti wọle tan, bẹni nwọn gbọ ohun Onigbo na ti o s ọ bayi pe, tilẹkun Nwọn si ti ilẹkun na, on pẹlu aja rẹ rin lọ si oju ọna ile na, nwọn tun kọ si ara ilẹkun ile na wipe, k a n ilẹkun. Aṣereke si kanlẹkun.

Bi o ti kanlẹkun gbaragada ni ilẹkun na si o si tun gbọ ohun Onigbo wipe, wọle Bi on pẹlu aja rẹ ti wọle t a n, nwọn r i tabili, ati apoti ijoko, ati iṣasun kan t i o mbẹ lori i n a, ṣugbọn nwọn ko r i ẹniti o gbe ka ina.

Onigbo tun fọhun, o ni ro iṣasun ti o mbẹ lori ina Aṣereke mu ṣibi, o si fi ro iṣasun na. Lẹhin ti o pari riro iṣasun na tan ni Onigbo wa bere lọwọ rẹ wipe, kilofẹ jẹ? Ninu gbogbo eyi, ẹru ko ba Aṣereke, o rope gbohun-gbohun ti iṣe ọ r ẹ on lo nsọrọ. O d a h u n wipe, amala ni ngo jẹ pẹlu ọ b ẹ gbẹgiri. Onjẹ y i n i Aṣereke fẹran lati ma jẹ nigba-gbogbo.

Onigbo sọ fun wipe, ki o gba tabili onjẹ ni abara nigba m ẹ t a, laijafara Aṣereke gba tabili n a n i abara akọkọ, awo ti nwọn de kanyọ, lẹkeji akaṣu amala nla kan yọ, bi o ti gba nigba kẹta bẹni awo kan yọ sori tabili, ikoko iṣasun gbe ara rẹ kuro lori ina, o si da ẹran kọndu-kọndu s'nu awo na pẹlu obẹ gbẹgiri. Onigbo tun fọhun, o ni onjẹ de, bẹrẹ si jẹun.

Aṣereke jẹun o yo, o si tun fun aja r ẹ. Lẹhin t i nwọn jẹun tan, o pe aja rẹ, o ni ako mọ kini a o tun ri nisisiyi.

Onigbo sọ fun Aṣereke pe, ki o ro iṣasun na lẹmẹta, bi o ti ro nigba kini, ẹkeji ati ẹkẹta, bẹni, i l e na ati ọgba rẹ ba di ẹiyẹ, o si fo lọ. Bi o t i n l ọ bẹ lo nwi fun A ṣ e r e k e wipe, emi gbohun-gbohun ọrẹ r ẹ ni, e r e igbọnran ni o jẹ ni, o digba o ṣe.

Bẹni Aṣereke ba ara rẹ ninu igbo ibiti o g b e ti mba gbohun-gbohun sọrọ leti odo abule wọn. "Ọmọ ti o ba gbọran yio jẹ amala" eyi na lo di owe titi di oni.

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, P. O. Box, 467, Lagos, Phone 23370.